Owe
KITA-KITA KOMỌ TI ARISIKI, KI A ṢIṢẸ BI ẸKN KO DỌGR AN

# ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

Asoje
ENIA BI IYA KOSI TANI JẸ S'ỌMỌ ỌLỌMỌ LORE

VOL. XIII No 702 LAGOS, SATURDAY AUGUST 19, - AUGUST 25, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)

# OLOYE OKOTIE-EBOH TE WAYA SI OKPARA KIO PADA WALE

## IPINLE IWO-ORUN GBONA JON-IN-JON-IN!

EKO— Asiwaju ẹgbẹ Alakuko ninu Igbimọ Alapapọse Oloye FESTUS OKOTIE-EBOH ni a gbọ wipe o tẹ waya ofcrafu ranṣẹ si Dokita OKPARA, Olẹtu ijọba Ila-orun ati Alakoso gbogbo ẹgbẹ N. C. N. C ti o wa nilu Oyinbo wipe kio dakun ge irin abẹwo rẹ, ki o pada wale kiakia nitoripe ipinlẹ Iwọ-orun Nigeria ko ṣ'ygbọ.

Ninu ọrọ rẹ ti o tẹ si waya, o sọ wipe, gẹgẹbi nkan ti nlọ si ni ipinle Iwọ-orun nisisiyi, mọ ni igbagbọ wipe o to o si ye ki o pada wa sile it rire ipinlẹ Iwọ-orun ilẹ Nigeria ngbona jon-in-jon-in, ki a le pe ipade awọn Ogunna gbogbo ẹgbẹ Alakuko lati ṣe aṣaro le lori.

L'ẹfiku, o tun sọ pe on paapa ṣeṣẹ ti ilẹ arin ipinle Iwọ-orun (Midwest) de ni, o ni gbogbo asiko ti on fiwa lohun ni nwon fi nran awọn enia wa ba on wipe ki on ranṣẹ si ọ ki o tete pada wa sile lati pe irade awọn igbimọ Eleto ẹgbẹ N.C.N.C ki a le ṣe aṣaro bi bayi ni ao fi awọn alatilẹhin ẹgbẹ sile fun iparun inidi nipa bilo ijọba lati ọwọ ẹgbẹ Afẹnifere (Action Group)?

Ọpọlọpọ ẹri iwa ininilara lowa lọwọ awọn ọlọpa Nigeria, paapa ọrọ n ko dun mọ, nwọn nṣe nkan wọnyi lati fi jẹ awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko niya nitoripe nwọn dapọmọ N.P.C ti nwọn kọ jẹ ki ẹgbẹ Afẹnifẹre le ṣe ijọba ile Nigeria.



OLOYE OKOTIE-EBOH

Ọrọ pọ nibẹ ki a duro bayi

## Olawoyin Jare Ejo Re

Ilorin - Ọgbeni J. S. Ọlawoyin ti iṣe akọwe fun ẹgbẹ Afenifere ile Ariwa, Oke-Ọya, ti nwọn ti mba rojọ esun wipe o gun Ọgbeni Momodu Ajisafe lobe, eniti iṣe Asiwaju ẹgbẹ Ọloko nilu Ọffa ri adajọ Kotu Ilorin, Ọgbeni C. M. Whitelow ti da lare wipe eri ti nwọn je ko mọyan lori.

(Ao ma gbọ iyoku lọsẹ ti o mbọ)

## Oba Adele Pada De Lati Ilu Oyinbo

**Eko**- Ariwo "Kab'yesi" ni o gbejikan lori kereni ọkọ ni Apapa, fun ọgunlọgọ awọn enia jankan-jankan ti nwọn lọ pade Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji, Ọba Eko, igbati o ti ilu Oyinbo de lọjọ Alaruba (Wednesday) ọsẹ yi, nigbati Igbakeji Alaga Igbimọ ibile Ilu Eko (L.T.C.) Ọgbeni Adeniran Ogunsanya lọ mu oba na jade lati inu ọkọ oju-omi ti o mu ọba wa ganiọ.



**Oba Adeniji Adele Keji**

Alaiyeluwa Ọba Adele pada de pelu Olori eleyinjuẹre iyawo rẹ Adejumọ Adukẹ Adeniji Adele ati Oloye rẹ Oloye A. B. Gbajumọ, Eletu Iwaṣe ti ilu Eko ni alafia.

Awọn enia pataki ti a le daruko ninu awọn ti o lọ pade rẹ ni T.O.S. Benson J. Modupe Johnson ati Malam Alhaji Musa Yar'Adua pelu awọn Aṣoju ilẹ okere nilu wa.

# ONIBARA ATATA MIRAN

Eniti a nwo ninu aworan yi ni okan ninu awon ti wa ko eko eluko ... ile eko giga ti Nottingham nilu Oyinbo.



Ogbeni M. N. Kasma lati Dodoma, ni Tanganyika ... ile ... ologere, Raleigh ... o ... nwo ti o mu Keke ologere kan dani ninu aworan yi.

# Jomo Kenyatta bo Kuro Ninu Igbekun

GATUNDU - Ogbeni Jomo Kenyatta Asiwaju awon egbe Oselu enia dudu ile Kenya (Nairobi) ti awon ijoba ilu na ti fi si isemo lati odun kejo s'ehin lori esun wipe o gbe ogun ti awon enia funfun ti o wa nile na, nitoripe o nja fun alafia ati igbadun gbogbo enia, dudu ati funfun pelu bakanna ni gbogbo wa nilati ma gbadun ile ti Olorun da fun wa. Awon ijoba ile Kenya ko te gba wipe awon enia ti Olorun da si ile na nilati ma je anfani igbadun ile won. Awon enia funfun die to de si ile na ni nwon ko gbogbo ile olora ibe mora nwon le awon enia dudu si asale ti ko le mu irugbin tere jade. Nwon ko gba wipe adajo kanna lo nilati wa fun enia dudu ati funfun. Iyen ni odun mejo sehin o.

Lehinna ni afefe ile awon enia dudu bere si fe kikan-kikan, ti o si nti gbogbo idena kuro fun alafia ati ominira ti o nwo ilu awon enia dudu.

(Wo yoku loju ewe kefa)

# KOTU DA OMO ILE GHANA KAN DURO FUN AYEWO L'OGBA WERE

EBUTE-METTA— Ninu Kotu Ebute-Metta ni nwon ti mu omo ile Ghana kan wa siwaju adajo fun esun wipe o je enia ti ko gbodo wo'lu Nigeria laisi Oluranlowo, ati pe o wo ile Nigeria lai gbawe ase; nigbati adajo woye odaran na ti o nje Limatta Ayoka, o pase ki awon da duro si ogba were ni Yaba fun ayewo Dokita.

Nigbati nwon pe ejo na niwaju adajo ni ojo Monday Dokita ti yio yewo tun bere fun ojo merinla si ki o le fi se ayewo re daradara.

Limatta yio tun pada de iwaju adajo ni ojo kerin-din logbon osu August, 1961.

# Oba-Ni-Gbogbo Fe Sile.

Salawu Ojikutu, eniti gbogbo enia mo gegebi Oba-ni-Gbogbo, ti fi iwe ipe si ta fun awon atajumose enia l'okunrin ati l'obinrin si ibi isile re ni ojo isinmi ti o mbo yi, (Sunday 20th August 1961) ni ... ti nwon npe ni "Gbogbo" Pagbogbe ilu Ilerodu.

Keke ologere Ogbon pupa ni Oba-ni-Gbogbo yo gun fi se ese rin ni ojo na.



## Akiyesi Fun Awon Omo Egbe Igbomina Parapo A.G. Alliance

Lati Owo Mr :- A.R. Orilonise

Aloko oro mi s'yin nipe oku iṣẹ wa. Ẹ si l.u ọrọ ilu Oluwa Q'a koni doju tiwa nibẹ. Amin ati aṣe, on ni pe iwọniba ọrọ ṣeki ni mo fẹ bayin s , atipe owe awọn Baba wa l'o npa owe kan pe "Agba to l a dan i siwaju ,io tẹlẹ tutr. Iru enyin baba ti eti bere wahala ti e nfi egbara eti ife inu yin han fun enikeni ni ile Igbomina O'uwa Olodumare koni 'o,u tiyin. Oluwa yio si mu ileri wa se, mole ki efi rra tale lati gbọ iwenba alaye ti mofe se fun yin yi dada, ki e si bere si se akiyesi iru wọn nkau ti o nsele. Oluwa k oni jeki ajel Egun-gun gbeh in eran o.

Ẹnyin ni erogun matidi okunrin ẹyin si ni atofa-nti mesutr, Lgbọn o je' ọpọlọpọ iyalenu fun mi lati leri w p ; bogo awọn mọ ile Igbon ire towa ninu ẹgbẹ N.P.C., ọrọ wọn dabi enipe eniti ko to nina t'o ndena oeri, a'ekun iya ni yio je, atipe ọpọlọpọ ninu emo ile Igbomina ti sonu. Ṣugbẹn Olu : ko'ctc ba wa da o. pada sile.

( Wo ẹyeku 'oju ewe k r un )

## PAGA ! OBINRIN NA TI KU.

Palermo (Sicily), Baba kan kove l iti gbawe aṣe igteyawe fun ọmọ rẹ obinrin ile s: ti nwọn ti ngbawe ṣ fu igbeyawo ni u Sicily, n gbati o daruko ọmọ re ni won sọ fun wipe, anu ṣe wa wipe ọmọ re obinrin ti ku gẹgẹbi awa ti mọ nhin

Nisisiyi, ọmọ rẹ obinrin na ti eruko rẹ ṣjẹ Signorina Concetta Bruno, ọmọ ọgbọn ọdun, ti gbelehun yi so di odi ti ko le lanu soro, ni lati re si Kotu fun iwe aṣẹ ti yio fi han wipe alaaye enia ni iṣe kotti ku, nitoripe nwon ti gba iwe oku elomiran ti nwon ;ẹ oloruko kanna ki ise ti on

Bibẹ kọ ko ni le gbeyawo.




## ... ATEGUN



GORDON Pirie omo ogbon odun l'ojo ori re ti a nwo ninu Aworan yi ni eniti o sare ije ninu ere fo, ile ti omi ti sodi petepete ti o si fi bori ninu ere ije ibuso meta ni Ilu Furfun ni London.

Ọgbeni Pirie kanna yi ni o koko bori ninu ere ije sisa fun ibuso meta nikan bi odun kejo s'ehin

## E YI OJO IPINNU PADA

Kaduna - Alhaji Ibrahim Imam ti ise Asiwaju Ala tako ninu ile igbimo Asofin ile Ariwa, ni o k si Ijoba ipinle Oke-Oya, (Nrthern Go vernment) w pe ki Gomina ipinle na, Ọla Sir Gawain Bell, w pe ki o yi ose meji ti o fi oke le lori fun awon enit Tiv lati fi sanwo girimoyan ti o le ni ẹgbẹdogbo ọnun ti wọn ni ki awọn enia na san fun ohun alumọni ijagboro ti nwọn ja ni Tiv bajẹ.

Ninu ọrọ Alhaji Imam nilu Kaduna lọjọ Satide, o so wi apakan wa ninu ofin ohun ti ijagboro ba bajẹ eyi ti o so wi a le gba wọn laye fun bi ọdun kan lati fi gba owo rẹ jọ.

## Iwe Irohin Wa L'adun Pip

## Igbamokan-din-lcdunrun Ni Ole Ja L'eKo, larin Osu Mefa

EKO - Ninu iroh'n lati ọwọ awọn ọlọpa ni a ti gbọ wipe igbamọkan-din-l dunrun ni ole ja nilu Eko ati agbegbe re larin oṣu mẹfa ti o kọja. Gbogbo nkan ti awọn ji ko lọ fere to ẹgb rin le-lgbẹjọ pọnun.

Ninu gbogbo re, eyit awọn ọlọpa ri gba pada ko ju orinle-lẹgẹta pọnun o din kan lọ, nwọn si sọ wipe ọpọlọpọ ni ole ti awọn ja ni asiko agogo kan oru si agogo mefa owurọ.

Awọn ọlọpa ... tarlọwọ ... ti ... fereṣe ile wọn ... 

Ki nwọn tun ... ile ... nigba gbogbo ... ni ... 

---

# APELEWON RI ISE TITUN

IKEJA — Ọkunrin kan ti o pe ara re ni apelẹwọn ti ọbọ niwaju adajọ Kotu Ikeja ni o gba ona ara ri iṣẹ titun nigbati ko ri iṣẹ ṣe fun ... pọ ọdun.

Oru ọ ọkunrin na nje Garuba Ṣokoto ti ko ni ibugbe ni o sọ wipe on jẹbi ẹsun ole ti aṣọ wiwọ ti Ọgbẹni Joshp Omogboni ti on ji o si wipe o ti igba mejidin-logun lọ ti on ti nwọn ẹwọn.

Ki adajọ to ṣe idajọ le lori ni Oyinbo oninurere kan ti o wa tẹri fun ẹjọ miran ni Kotu, Ọgbẹni Williams Haywood ti ilese Cadbury Exbort Limited Apapa dide niwaju adajọ ti o si bere fun u, wipe da silẹ on yio fi wọṣẹ lẹsẹkẹsẹ ki o le tun igbesi aiye re ṣe.

Adajọ sọ wipe on yio gba ẹbẹ oninurere yi, Ọgbẹni Williams Haywood, o si da silẹ ki o ma lọ, Ọgbẹni Haywood si fi mọto re wa Garuba lọ sile iṣẹ rẹ nibiti o ti bere iṣe lẹsẹkanna.

Ofi tirẹ silẹ gbọ ti eni ẹleni, Oluwa Ọlọrun ni o nbo gbo tirẹ.

---

## Abode Jomo Kenyatta

NAIROBI — Ijọba ilu Kenya ti kesi gbogbo Oniwe irohin wipe ki nwọn mura silẹ lati ọjọ Jimọ titi di ọjọ Alamisi lati le ṣe irohin kikun nipa dide Jomọ Kenyatta si Gatundu, iwọn ibuso mẹdogun si ihin.

Nitoripe ako ni fun wọn ni aye kọja wakati kan pere nigbati a ba kesi wọn lati wa wa ba ọkọ lọ si Gatundu nibiti Aṣiwaju awọn Kikuyu yio de si lati Maralal, ti o jẹ ọgọsan ibuso silu Nairobi.


Fun ina dida ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri rà nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, inẹ-titàn ati lati mã fi yànè Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!


# OKU'JA WOLU

NIBGATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O NRA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ṢE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI ỌJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

## E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin ELETI-OFE

# AKIYESI FUN AWON OMO EGBE IGBOMINA PARAPO A.G ALLIANCE

( O bere loju ewe keji )

Enyin omo Egbe N.P.C. - ye ki e pe Aro Inuyin a'i odefin Inuyin ki ere ero yi wo-wipe ife-afe akuko, koderu, ibi k'apaje l'omo o damilojo wipe gbogbo omo ile Igbomina tew..."niun" Egbe Oloko, N.P.C. keleri Asiri awon "H usa" 'Afej tan l'e nse kinni Ikan toyayin lori tesi idud'ninu yin Oju ko tiyin a a kolojin Awon ara Ilorin n t a n yin won ti o'un beyin leru bi eran enyin na situn nitele w n sugbon Adura mi n pe oluwa k'eye yin kuro nibe ti ofi yin si u Imojo aye 'kini Imole aiye na ni pe "Dwision" ti awon omo enia g'd ra fun Oluwa no le tete to wa lowo.

Sugbon enyin omo egbe N.P.C mo fe ki e ranti wipe ewe kan wi bayi pe RIRO NITI ENIA ŞIŞE NI.I OLUWA Em si m dajo wipe B'ope iti, Ogun odun mo wa ka ola o. Sugbon itiri enyin fi oju si ena k o gbate lo epada lora anu ati ona ojo, ti e nrin ki ise ena tara lowa nibe, e jeki a ni i fiowo sowo ki e ma b a g b e ilu Baba yin ta, e owo a on ti mof darak, woeyi ki a wo iduro won inu egbe Igbomina Parapo.

Eni akoko 1, Olola wa M . D. A. Ogundele 2, M.A Opeloyeru (3) P. B. Olatunde (4 ) Samuel Adeniran (5) Anthony Awodiji (6) Joseph A d e n y ' 7) Mr Ajayomi (8) J. Bandele (9) F O. Atunbi ati irn awon enia bebe t'o j e o m o ile Igbomina ti won ni ifarada ati gbogbo orişirişi n k a n ti w o n eri. Sugbon adura mi si gbogbo won nipe Oluwa alanu yio gba wor l o i ni şiwi gbogbo wa yio k o ere oko dele oromi na koro tobe, mogba eyin em egbe niyanju wipe ki atunbo mura lati wa ilosiwaju Ile Igbomina, Eyin baba wa, eyin Qmokunrin wa, e maşe ko are okan rara. Oluwa yio dawa lare nigbo gbo ona ti ab ng a o.

Eyin omo egbe Oloko, ( N P.C. ) eje eaun okan m wipe awon "Hausa" tun nfi han yin gbangba-gbangba pe won ni eyin kole bo kuro ninu Iya ti won la boyin loran, oje e mo itumo oko, sepe eyin na mo wipe awon eru loma nroko laye lailai, ti awon Baba wa nra eru. Sugbon aiye tikuro tee O sese leyin na nfi ilu tiwon g b e bi a sile wa ilu orilu. Eronu wo e wo gbogbo ile yoku talotun mrole, Oluwa Olodomare koni jeki e sonu jinna. O je amona mi siyi e wa i aia no ogbe eleru egbe olomo ni egbe Igbomina Parapo. Ki i teh gbogbo wa le dara o ee tun nagbe Iyoku ni ore t'oniba. Oluwa Olodumare ko je ki Igbomina siye wa da dele o. Ipade wa bi eyin o

**E ma ka iwe irohin Eleti-ofe ti o kun fun Irohin Aladun L'osose**

# NWON NFI OKO OFURUFU WON'LE.



Ijoba Apapose ile Rhodesia ati Nyasaland laipe yi tun gbe ise wiwon ile Apapose awon ile na fun awon alagbase ise, Fairey Air Surveys ti ilu Rhodesia.

Gbogbo ibiti awon fe ki awon won la Barronga ni Ariwa Nyasaland nitosi odo Bangweulu o fi d e ile oko rito niha Gusu Bulawayo ni Rhodesia. Omo enia dudu ni a nwo ti o nfi ero wo ile lati inu oko ofurufu yi.

BERE OLULOWO EGBOGI AWON FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"

Fun Iteju tabi fifo Apo Ile Ito Kidney - Bladder fun Okunrin ati Obinrin bi awon amodi wonyi ba nyo o lenu Ehin didun eti ile ito ito jijo enia, ito riru, rukuruku Pipon tabi tirun, Jakuregbe, Ibaradi wiwo, orunkun, owo, ese Ejika wiwu tabi rito.



Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara konkon tabi kiakia, didaji loru nigbakugba, ati orisirisi awon aisan tabi amodi bawonyi ni egbogi ajebidan yi yio wo sàn lara re ni kia kia ti alafia yo si de si o. Meji re ko si ni Ilu Naijiria nitorina sora ki awon eleru tabi awon eni to tirobi ma ta orisi omiran ti ko ni lari fun o, mase gba tara o!

Owo re je Sile Mefa abo 6/6 owo oko sile meji abo (2/6d)

Bere Egbogi yi ni Sobu awon Saro ti won npe ni:-

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos, Phone: 22878 Nigeria.
(Oja Ita Faji)

ATI NI AWON SOBU IBADAN:-
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA IBADAN.
ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES
APATA-AIYERAIYE STREET, ADE OYO, IBADAN.

## OTITE ILU FIJI




AWON ANTI a nwo yi niti otite titun tilu Fiji, ti Ayaworan Ogbeni Michael Goaman ya lkipe yi fun ijoba ilu Fiji.

Awon otite titun na jeti otite oni kobo meje ti ita nna ewe'ko pupa wa lara re ninu awon eleru pelu aworan Alaiyeluwa oba obinrin Elizabeth Keji.

HIRE

PURCHASE

Facilities

Now Available For

| | |
|---|---|
| KELVINATOR | Appliances |
| OLIVETTI | Typewriters |
| SANYO | T.V. Sets |
| HOOVER | Appliances |
| AGRICULTURAL | Machinery |

For LAGOS AREA Only

From

LEVENTIS

Marina & Iddo

Tel. Marina 24831. Iddo : 23872

## O JEUN JU IKAN LO

FRANCE– Okunrin kan ti oruko re nje Jean Aupetit omo odun metadin-logun, ni eniti o kere ju, ti o si ri rele nge ju ninu awon ti o dije onje jije ni Chimnon nile Faranse ni ale ojo Atalata (Tuesday) tokoja yi.

Nigbati awon ti a ro wipe won le jeun ju ti awon ijo dije onje na nyi sutu lori Tabili, fun iseju mokan-le-logun ni Jean fi je akara olobe ti o ga ni esun meji-din-logun (18 inches) iwon ifun eran meji (2 lbs) iwon werakasi kan (1 lb) iwon buredi kan (1 lb) o wa fi igo oti eso ajara meji san wale sinu agbedu ikun re.

Lehinna ni Jean, ti 'o je wipe ise akara l'o nse sese wa dari lo sile lo je onje ale ki o to sun.

Nwon fun Jean loye eniti o le jeun julo nile Faranse fun odun 1961.

Printed & Published By The Union Printing and Publishing Company 24, Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370